OWE
Ipako onipako f'ari
ẹnịẹlẹni ni i ri t'ẹni

# Irohin Yoruba

VOL. IX No. 153. Monday March 15, 1954 KOBO KAN (1d)

E MA A POLOWO
Oja Nyin Sinu
Iwe Irohin Yoruba

# Awon Adahunse So Gende Okunrin Di Obirin

Nigbati o di obirin

CROYDON-LONDON--Lẹnulọloyi ni Ọgbẹni Robert Cowell ẹni ọdun marundilogoji, ọmọ Ọgagun [Major General] Ọlọla Earnest Cowell K. B E., C. B., D. S. O. Dọkita pataki fun Olọgbe Ọba George Kẹfa ati Alakoso awọn Dọkita ni Eisenhower's North African Campaign, iya rẹ ni Dorothy Elizabeth Cowell di obirin lẹhinti ọpọ awọn Dọkita ṣiṣẹ pupọ si i lara, orukọ ti o njẹ nisisiyi ni Roberta Elizabeth Cowell.

Ohun ti o ya awọn Dọkita lẹnu pupọ ninu iyipada na ni pe eyi ni akọkọ ti nwọn kọ ṣe iru iṣẹ bẹẹ fun ọkunrin ti o ti bimọ, nitoripe ọkunrin na ti bi ọmọ obirin meji ki o to di obirin. O ni arakunrin kan ati arabirin kan, awọn obi wọn si jọ tọ wọn pọ ni. O lọ kọ ẹkọ nipa irin-



ROBERT COWELL
(Nigbati o wa ni ọkunrin)

ṣẹ ẹrọ (engineering) ni London University, o si gbadun ki o ma a fi mọto ba wọn sare ije, eyiti o ṣe kẹhin ni ti International Road Race ni 1948. Lati aṣeko na ni ami ara ti nfu u lati ni iyipada yi.

Nigbati Iyawo Ọgbẹni Robert Cowell ẹniti o yi orukọ rẹ pada si Roberta Elizabeth Cowell nisisiyi gburo pe ọkọ on di obirin, o ni ni gbogbo aṣeko ti awọn wu ni t'ọkọ t'aya ifẹ gidi wa larin awọn-edeaiyede ko si rara, ṣugbọn nigbati Ọlọrun fi awọn ọmọ ta wọn lọrẹ ni on ri i pe ko ni ifẹ si awọn ọmọ na, on si ti fẹrẹ binu si i ki on to fi abuku kan iwa alaibikita rẹ.

O si tun sọ pe nipa wiwọ awọn ẹwu on ni o ti bẹrẹsi ya on lẹnu pe kini iba fa a iru iwa bayi. Iyawo rẹ na si ti di Iyaafin Zelma Paul, lẹhin ti o ti kọ ọ silẹ nipa aibikita fun on ati awọn ọmọ ti o bi fun un, awọn ọmọ mejeji na ti o si bi fun "adamọdi obirin" na ko ronu rara nipa baba wọn ti o di obirin.

Ọmọ-kunrin na si ti mu iwe ọjọbi rẹ lọ si ọdọ ilaṣẹ Iwe Ọjọbi ilu wọn Ọgbẹni Phillip J. Stevens, gbogbo ibiti a ti kọ si ibẹ pe ọkunrin ni ọmọ na ni a si yi pada si obirin ati orukọ ọkunrin ti o ti njẹ ni - yipada si t'obirin. Alaṣẹ Iwe ọjọbi na si fi ọwọ si i.



ROBERTA ELIZABETH COWELL

## Ija-igboro Bere N'lu Ibo

AKUNA AKUNA--Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogbọn oṣu ti o koja yi ni awọn ara ilu Ikwo ti agbegbe Abakaliki l'ọkunrin ati l'obirin fi ake kori pe, ohun ti yio ba gba ni awọn yio fi fun un awọn ko ni san ẹkunwo-owo-ori ti Ijọba fi kun ori fun ẹkọ.

Nigbati awọn enia wọnyi jade nwọn fi ibinu lọ ba Ajẹlẹ Kekere (District Officer) nigbati o ri i pe apa awọn Ọlọpa adugbo ibẹ ko ka wọn ni o ba ranṣẹ pe ẹgbẹ-ogun Ọlọpa meji lati Abakaliki, nigbati awọn ọlọpa yi de ti nwọn fi ẹefin-oloro (Tear gas) tu wọn ka, ti nwọn ko gbọ ni nwọn ba yin ikibọn mẹfa, nigbati nwọn

[Wo oju ewe kẹrin]

## Egbe N.C.N.C. Ibadan Nfa Ijongbon

IBADAN-Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni awọn iaεd··ka ... Ẹgbẹ N.C.N.C. Ibadan ebagun-jọ si ojude Radio [Radio Square] Mapo, ti nwọn si bẹrẹ si ilu awọn enia ti o faramọ Ẹgbẹ Action Group ni alubalẹ. Nwọn si dogbẹ si Karimu Adedokun ati Karimu S. Ayind lara pupọ.

Lori ọran yi awọn ọ o pa ti fanṣẹ pe Ọgbẹni B. Adegoke Adelabu Olori Ẹgbẹ N. C. N. C. Ibadan ati awọn isongbe rẹ mẹta Elẹsinmẹta, Layi Fijabi (Akọda) ati Yesufu Alamu lati wadi ohun ti o fa a ki awọn enia wọn to ma a fa iru ijọngbọn bẹ ẹ, onikaluku wọn si sọ l'ẹnu wọn t'awọn ọọọa na.

Awọn mẹjẹ ni ọlọpa ti mu nisisiyi ti nwọn si mba ṣe ẹjọ lori iwa ijandukụ ti nwọn hu lati ma a lọ da agbo pade awọn Ẹgbẹ Action Group, eyiti nwọn ṣe ni adugbo Oke-Foko Ibadan. Bi nwọn ba ti pari ẹjọ wọn si ẹ o ma a gbọ ọ.

## A Da Egbe Action Group Sile L'oke Okun

ABOSSO-G. C.- Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkandilogun oṣu kẹrin odun ti o koja yi ni nkan bi ago mẹrin abọ irọlẹ ni awọn enia pataki pataki wa da Ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) silẹ ni ilu yi. Ọgbẹni R. A. Belo ni o ṣe alaga lọjọ na. Alfa F. A. Osho, Wọn pataki ni o gba adura pataki fun ifidimulẹ Ẹka Ẹgbẹ na ati fun igbega gbogbo Ẹgbẹ na kakiri.

Wo oju ewe kẹrin

## Awolowo Ngoke Agba

IBADAN--Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ Olori Ẹgbẹ Action Group ati Alakoso Igbimọ Aṣofin Ijọba Iwọ-Orun Nigeria ṣe ajọyọ Ajọdun ọdun karundinladọta ti a ti bi i sinu ile aiye.

Awọn Ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre "Action Group Youth Association" si pe apejẹ pataki kan si agbala ile onjẹ "Central Hotel" Ibadan fun ajọyọ Ọjọbi Ọlọla na, ẹniti o ṣe alaga apejẹ pataki na ni Professor Ọladele Ajọsẹ. Awọn ọlọla ati awọn enia pataki pataki kakiri ilu ti o wa ni abẹ Ijọba Iwọ-Orun Nigeria ni o pesẹ sibi apejẹ na.

Nwọn sọ ọrọ iwuri pupọ nipa bi Ọlọla na, Ọbafẹmi Awolọwọ ti ṣe nlo igbesi aiye rẹ ni ọna ti o tọ ti o si yẹ gẹgẹ bi o ti tọ fun Aṣiwaju ninu Ẹgbẹ Iṣelu lati ma a ṣe. On papa si sọ bi o ti ṣe lo igbesi aiye rẹ si ki o to le ma a ri ilọsiwaju ninu ohun gbogbo ti o ba ndawọle lati ṣe, o si gba awọn enia ni iyanju ohun ti o tọ ki enia ma a fi ara mọ ati eyi ti o yẹ ki enia ti yẹra fun.

Ki Ọlọrun da emi rẹ si, ki o le ṣe ọpọ ọdun si i l'aiye pẹlu alafia ati inudidun.



ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ



